# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TUNI GBOGBO LAWA

710 WEDNESDAY, JUNE 3, 1964 (2D)


## IJỌBA PE IMOUDU L'ẸJỌ

EKO:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹaimọye awọn enia ti o wa si Ile ẹjọ giga kan l'Eko nigbati awọn Ọlọpa mu Ọgbẹni Micheal Ominibus Imodu, Asiwaju Agba Igbimọ ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ Naijiria wa siwaju adajọ fun ẹsun pe o ko awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣiṣẹ ṣe iwọde lodi si ofin ati aṣẹ Ijọba ni ọjọ Abamẹta ti iṣe Ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi.

Ọlọpa ti o ba Imoudu ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọgbọnjọ oṣu yi ni Imoudu ko awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣiṣẹ lẹhin ti nwọn si nṣe iwọde ni Yaba bọ wa si Eko.

Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju pe lati ọjọ na ni awọn ti nwa Imoudu ti awọn ko si ri nitoripe o salọ.

Ṣugbọn Ọgbẹni Imoudu bu ẹnu atẹ lu ọrọ ti Ọlọpa na sọ, o si ṣe alaye pe, on ngbọ gbogbo ohunti nwọn nsọ lori ẹrọ asọrọmagbesi pe, nwọn nwa on Ọgbẹni Imoudu ni on fẹ ri i daju pe, awọn oṣiṣẹ da iṣẹ silẹ gẹgẹbi ero ati ipinnu ti awọn ṣe, lẹhin na ki on wa fi ara han fun awọn Ọlọpa, ki nwọn ṣe on bi nwọn ba ti fẹ. O wa pari ọrọ rẹ pe, "Ẹ sọ pe mo salọ, fun kini? Emi ti iṣe iru Asiwaju ti ko le faiya ran iṣoro, ẹru, ẹru Ijọba ko bami depo Ọlọpa"

Adajọ ti yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi lori iduro igba ponun (£200). Bi awọn ba ti pari ẹjọ na si, ẹ o ma gbọ

## Alhaji Adebọla Jade Ni Ile—Iwosan

# AWỌN OṢIṢẸ DA IṢẸ SILẸ

EKO:— Gbogbo enia tẹrẹsi pooyi yikakiri gbogbo igboro ilu Eko lana bi ṣia ba-a-ba nigbati gbogbo wọn jade lọ lati lọ ra ẹja ṣugbọn ti nwọn ko ri ọna gba lati wọle nitoripe gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba ati ti awọn Oyinbo onişowo ni nwọn ti da iṣẹ silẹ

Irohin fi ye wa pe nigbati awọn enia na sare kakiri lati ra ẹja wọn ti nwọn ko si ri ibi ra wọn ba pada sile wọn lọwọ ofo.

Irohin fi ye wa pe gbogbo awọn enia ti nwọn lọ si Ile-Iṣẹ waya ati ifipe ran ṣẹ lati tẹ waya ati lati ra ontẹ Ijọba pẹlu awọn ti ọja tuntun ẹṣẹ de fun lati ilu Oyinbo ni nwọn ko ri aye gba ohun ti nwọn fẹ.

Onironin wa kan fi ye wa pe, gbogbo awọn enia ti nwọn fẹ lọ si ilu okere ati Oke-Okun ni ana ni nwọn ko tun le lọ mọ, nitoripe awọn oṣiṣẹ ọkọ ofurufu da iṣẹ silẹ

A gbọ wipe nigbati awọn enia na duro ni Ikẹja titi ti awọn oṣiṣẹ kọ ipakọ si wọn ti nwọn ko si da wọn lohun ni nwọn ba pada wale lati Ibudo ọkọ ofurufu Ikẹja.

Bakanna ni awọn oṣiṣẹ ọkọ reluwe ti gbogbo wọn da iṣẹ silẹ ni ana kanna ti nwọn ko si da awọn enia ti o ba lọ si ọdọ wọn lohun

Gbogbo awọn ero ti nwọn joko si Iddo lana lati lọsi idalẹ ni wọn ko ri enia da wọn lohun lana nigbati wọn joko ti idi nta wọn si gbogbo wọn ba tuka lọ si ile wọn awọn elomiran ninu



Ọgbẹni Goodluck

wọn si binu lọwọ Bọlẹkaja lọ si Ibadan tabi Abẹokuta.

Irohin tun fi ye wa pe gbogbo awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ awọn Oyinbo oniso wo ni wọn da iṣẹ silẹ ti wọn ko si ta ọja fun gbobgo awọn onibara wọn ti nba wọn wa raja

Diẹ ninu ile iṣẹ awọn Oyinbo onisowo ti nwọn da iṣe silẹ lana ni awọn bii U.T.C., P.Z., U.A.C. ati bẹbẹlọ



Ọgbẹni H. P. Adebọla

Irohin fi ye wa pe, awọn osisẹ isẹ ẹrọ manamana da iṣẹ silẹ ni ana ati awọn osisẹ asọrọmọgbesi N.B.C ati W.N.B.S.

Onirohin wa kan fi ye wa pe ọgbẹni Badejọ ti sẹ olori isẹ ẹrọ asọrọmọgbesi kesi gbogbo awọn osisẹ pe ki wọn ma se dasẹ silẹ ki wọn duro de ohun ti Ijọba yio ṣe titi jalẹ ọsẹ yi.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn osisẹ Ijọba ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Ipinlẹ Ila Orun ati Ipinlẹ Ariwa ni awọn osisẹ da iṣẹ wọn silẹ ti nwọn si joko tẹtẹrẹ ti nwọn ko fi ọwọ kan iṣẹ kan ṣe.

A gbọ pe, gbogbo awọn enia na ni awọn lọ si ibi iṣẹ kosi ẹniti o pẹdin ninu wọn, ṣugbọn nwọn ko fi ọwọ kan iṣẹ wọn ṣe.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa pe, ọgbẹni J. C. Obande sọ fun on pe on yio ba gbogbo awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ sọrọ ni owurọ yi, on yio si fun wọn ni iwe ipinnu Apapọ Ijọba lori ọrọ na.

Alhaji H. P. Adebọla ti iṣe Asiwaju ẹgbẹ awọn osisẹ ti o wa ni ile iwosan Igbobi ti jade, awọn ọlọpa mulọ si kotu ni ana, sugbon

WO OJU EWE KẸFA

## Okpara Wọ Ibadan Gẹgẹbi Ọba

IBADAN:— Ọrọ di boo lọ o ya fun mi gbogbo ilu si gbojikan fun ariwo ti awọn ara ilu nsare lọ pade Dọkita Michael Okpara Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ loju ọna nigbati irohin kan wọn pe, Alakoso Ijọba na wọ igboro ilu Ibadan ni deede agogo mọkanla owurọ ana ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ keji oṣu yi.



DR M I Okpara
Alakoso Ipinlẹ Ila Orun Nigeria

Irohin fi ye pe ni Idiyaunrẹ ti iṣe ibusọ mejila si Ibadan ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ti to lọ pade rẹ loju ọna ti awọn ọmọ ẹgbẹ mejeji si fi tayọtayọ ki i ku abọ.

Onirohin wa fi ye wa pe, nigbati o wọ ilu awọn enia miran gun ori igi lọ ki nwọn le ri i awọn miran si sare lọ gun ori ile pẹtẹsi nitori ọpọ enia.

Bi Dọkita Okpara ti ṣe wọlu ilu ni ana, mọto mẹfa ni Apapọ Ijọba fi ko awọn Ọlọpa pẹlu ponpo lọwọ wọn lọ si Ibadan nitori aibamọ.

Lẹsẹkẹsẹ ti Okpara wọ Ibadan oju olori Alhaji Adegoke Adelabu ni o kọkọ lọ, o si gbe ododo si ori iboji rẹ

Lẹhin ti Dokita Okpara kuro ni iboji Alhaji Adelabu ni oba lọ si Ọyọ osi pada wasi Ibadan wa sun ni alẹ ana.

Bi o ti nlọ ibiti on lọ yi mọto mẹfa ti o ko ero ni okun dẹmudẹmu ti awọn Ọlọpa ni o tẹle Dokita Okpara lẹhin titi.

Bẹni awọn Ọlọpa na yio yika gbogbo ibiti o ba nlọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun titi di asiko ti yio pari ipade rẹ.

Dokita Okpara lọ si ile Oloye S. L. Akintọla ṣugbọn ko ba nile o si kọ iwe silẹ ninu Iwe ibẹwo awọn alejo

# IROHIN IMỌLE.

ẸSIN ỌRỌ WA—'IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA
Ẹ Kọwe si:- OLOTU IROHIN IMỌLẸ
FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN
EKO— ṢILE MẸJỌ KỌBỌ MẸJỌ(8/8)
ILU MIRAN NI NIJIRIA ATI OKE OKUN ṢILE MẸTALA (13)


## ỌRỌ OLOTU

## IMỌRAN F'AWỌN OLOYE IBADAN

O jẹ iṣẹ awọn iwe Ir hin lati n a a fun gbogbo enia ni ojulowo imọran gẹgẹbi o ti tọ ati bi o ti yẹ, eyi ti a lero pe yio ṣe anfani fun awọn Alaṣẹ Ijọba ati gbogbo awọn ara ilu, ti ko ni jẹ abuku, a fi abukun, bi awọn ba le gba imọran na, ti nwọn ko si kọ eti didi si i.

Gẹgẹbi irohin ti o jade ninu Iwe Irohin wa ti ọsẹ to kọja yi n: pa iku Ọba Alaiyeluwa Isaac Babalọla Mabayọjẹ Akinyẹle Olubadan, Bi ẹni rere ba lọ, ẹni rere ni a si fi rọpo rẹ, nitorina, a fẹ ki awọn Oloye Afọbajẹ Ibadan fi ara balẹ lati yan ẹniti Oye na bọ tọ si ninu awọn ti o ni ẹtọ lati jẹ Ọba, Iru ẹni na si ni lati yẹ ni gbogbo ọnu lati rọpo Ọba ti o W'aja yi.

Bi o ti wu ki oluwarẹ ri ẹtọ ati jẹ Ọba na si to, bi ko ba ni iwa ko dara rara nitoripe ẹniti yio ba ma ako ori tutu ati ori gbigbẹ jọ ni lati jẹ ẹniti o ni ọpọlọpọ suuru ati laakaye.

Pataki ohun ti Awọn oniwe Irohin Imọlẹ fẹ sọ fun gbogbo awọn ara Ibadan paapa fun awọn ọmọ Oloye ti o ni ẹtọ lati jẹ oye nipe Ọba ti o w'aja ti lo asiko rẹ si rere na. Iyoku ku si awọn ara ilu lọwọ, paapajulọ awọn Oloye Afọbajẹ.

Ko ni ohun ti o tọ ti osi yẹ ki a ma a gbe rogbodiyan dani tabi ki a ma a gbe ẹgun dide ti ara wa lehin iku Ọba rere na nipa pe, eyi a ni on ni ati jẹ Ọba kan tọhun atun dide pe on ni,

L'aiye atijọ bi nwọn ba ndu ipo Ọba bi awọn oloye afọbajẹ bati yan ẹni kan ninu awọn ti o du oye na gbo gbo awọn yoku ni ylo fi ara mọ ọ,

Ẹniti awọn ẹti ọba ati awọn oloye Afọbajẹ ati ara ilu bati ri pe o tọ si on ni ki gbogbo nyin gba fun tọwọ tẹsẹ Bi awọn apa kan ba ki ṣe atako iru ata ko bẹ yio mu ilu dasi meji yio si mu ọtẹ wa Adanu nla nla patapata ni ọtẹ si ma a da silẹ gẹgẹbi ọpọlọpọ wa ti ṣe mọ.

Ẹnyin onkawe wa melo melo ni awọn ẹni ọla ti idagiri tabi iku oro ti lu ọmọ wọn tabi iyawo wọn pa? Melo melo enia ti ile wọn jasi tita laiṣe pe nwọn jẹ gbese? ati melo melo a'agba enia ti nwọn ti ku iku oro ati iku ojiji nipa ọtẹ ṣiṣe ni ile Yoruba?

Ki Oluwa Olodumare ma jẹki a tun ri ọtẹ mọ o. Ọtẹ maa ntẹ ni ni, ọtẹ a si tun maa ngmu airoju ati airaye ba b ale ile, awọn Oloye ati gbogbo awọn ara ilu. Ohun ti gbogbo ilẹ Yoruba nia fun loni alafia, ifaiyabalẹ isol.an, idagbasoke on ilọsiwaju nitorina, ki awọn Oloye Afọbajẹ Ibadan gba imọran wa kekere yi.

Batabata ni ọmọde iwi niwaju baba rẹ, baba rẹ a si fi ayọ gbaa. Aabọ ọrọ ni a sọ fun ọmọlu-wabi, bi o ba de inu rẹ, a di odidi.

# Ẹ Wo Okunrin Yi

**Lati ọwọ S. O. JAIYE, Eko**

Ọrọ mẹta yii jade ninu ọrọ Ọlọrun. Ọrọ yi nigbakugba ti mo ba ka ọrọ Ọlọrun awọn ero pupọ a nia sọ si mi lọkan wipe kini de ti ọrọ ara yi jade ninu ọrọ Ọlọrun Inu awọn enia wo ni a nlo ede pataki yi fun ninu ọrọ. Ọlọrun bi ko ṣe awọn ẹni pataki to ṣiṣẹ rere jalẹ lode aiye? Ẹniti Ọlọrun papa j ri si iṣẹ rẹ wipe o ṣeun pataki. Tabi ki o tọka si awọn iṣe abami to ṣe ni aiye rẹ.

Ni idakeji bi ibanujẹ to sọ ori agba kodo bẹ, ba ọmọ enia a tun le wipe wo ọkunrin na ti ibanujẹ teri rẹ ba. Emi ba kẹdun a ma fi ara han nipa rẹ.

Iru ipo bayi ni Jesu wa nigbati O sọ fun Maria Iya rẹ wipe Iya wo ọmọ rẹ eyi ti ise John. Lẹhin na O wipe ọmọ wo Iya rẹ

Eyi ni pe Jesu sọ eyi fun itọni wipe ko si ohun kan bi isoro to wa to le mu wa gbagbe awọn to yẹ fun iran ti ninu aiye ẹni.

Fun awọn ọrọ diẹ ti mo sọ loke iwe yi bẹni mo fi ọwọ fun Baba wa o'ogbe Olubadan Isaac Akinyele, baba olotọ ninu Ẹmi Oluwa, ninu Ẹsin to peju. Ọba ti o jẹ onigbagbọ ti a ko ri iru re ninu ọpọ enia.

Nigbati mo ntẹti si ẹrọ asọrọ-ma-gbesi (redio) o jẹ ohun iwuri fun gbogbo awọn lehin Jesu lati gbọ iru iṣẹ, iṣẹ ati igbesi bi ba wa yi nigbati o wa ninu aiye.

Fun igbati o wa lori itẹ gẹgẹ bi Ọba lori ilu nla Iba dan ko tori okele tabi owo ba Ijọ rẹ jẹ rara. Tabi ki o mu idarudapọ wa si ilu Ibanan.

Bakanna ni o jẹ aṣaju ninu ihinrere Jesu. Laiye oni o sọrọ pupọ nati jẹ ọba ilu kan ki a tun ri aye pa ọrọ Mimọ Ọlọrun mọ, Nitorina Ibukun ni fun oruko Baba ati ọba rere yi Ọrọ Ọlọrun wipe wo ọkunrin na.

Tani ọkọnrin yi? Baba wa n nu Ẹmi, Ọba wa rere lori itẹ rẹ. Wo bi awọn alagbara ti nṣubu ninu ija aiye

Ọla ati ọwọ ni fun iranti o'a Isaac Akinyele ti a gbọ wipe o wọ aja. Ti aja ba le da awọn wọ ọ lọ si u ọrun ni awa iba bẹ ki o da baba rere yi pada fun wa.

Ah! wo bi awọn alagbara ti nre afara aiye yi kọja lọ si ọrun alakeji, ilu aiyeraiye.

Ye! ẹnyin ọmọ Lagelu sọkun,

Lori Igi nla o wo lulẹ,

Larin omi enia to nwọpọ,



Ọgbẹni S. O. JAIYE

Fun ohun ọfọ lori baba ọwọn,

Wo ọkunrin alagbara Olubadan,

Ti iṣẹ rẹ, iwa rẹ wu ọmọ enia,

To fẹran iwa ododo ninu esu,

To wipe wo ọkunrin jẹjẹ yi,

Lori oke Mapo wo yika kiri,

Bi ẹnikan wa ti ko gbọ ohun rere,

Ẹkun ẹni ami ororo to ti yan tẹlẹ,

Fun ipo ọla ọba ati ihin rere rẹ,

Kini ki awi lori iku baba nla yi?

Wo aiye Ọba Akinyele dun ọrun rẹ?

Iwọ ọmọ birin ni Oke Mapo ninu ẹwa rẹ?

Kini ki a sọ lori Iku Ọba rere yi,

Iwọ ọmọ kunrin akọni Ibadan ọmọ Lagelu.

Nitori Ododo rẹ pọ jakejado oke Mopo,

To de Ibadan lade ẹwa wo Ilu nla yi.

Ti iṣẹ ilu Ijọba Iwọ Orun Ilẹ Naijiria.

Odigbọṣe Baba.

Odigbọṣe Ọba

Odigbọṣe Ẹni Ọwọ

Ah! Odigbọṣe.

# IWE SI OLOTU

## Akinmorin, E Fi Eyi S'ero

Olotu jowo gba mi ni aye die ninu iwe re oloyin momo ti o njade lojojumo ti o kun fun ogbon oye lati ba awon enia ilu Akinmori so oro ti odun mi lokan, nitoripe Yoruba ni omo ale ni fi owo osi juwe ile baba re. Bi ilu eni kere, bi o si tobi a ni lati mo ponle ki a si mo wa ilosiwaju re nigba gbogbo.

Laipe yi ni a gbo wipe awon ole ti so ilu Akinmorin di ibo won, ko si ojulowo omo ilu Akinmorin ti inu re dun si iru iwa bayi Nitoripe lati ojo ti mo ti daiye emi ko gbo ri pe ole nja pupo ninu ilu Akinmorin

Mo be enyin agbagba, odo paapa gbogbo enyin omo ilu Akinmorin ti o wa ni idale pe, ki won je ki a dide fun ilosiwaju ati idagbasoke ilu wa. E jeki a pe ara wa jo ki a fimukonu ki a fi ikunlukun ki ilu wa le ni ilosiwaju bi awon ilu ... nla to wa ni Iwo-Oorun Naijiria.

Enyin ole ti eje ki a won onile sun loru, e lo tepa mo se nyin daada nigbati awon egbe re nlo sibi ise enyin nson losan, ejowo e ba wa rao ilu wa lowo ki e mo j le mo.

Mo dupe lowo nyin Olotu fun aye ti e gba mi

Emi ni
Young Ade
AKINMORIN

## Eyi Ya Mi Lenu

Pelu iteriba ni mo fi toro aye die lodo Olotu iwe Irohin Imole lati fesi si oro kan to jade ninu gbogbo iwe Irohin ni ede Oyinbo pe, egbe Demo ati egbe Afenifere pe oro won ti wo, won si ti setan lati darapo lati ma se Ijoba Ipinle Iwo Oran. Ko si eni ti yio ka oro na ti ko ni se ni ka yeh ti ko si ni ro inu aroun ro.



Oloye Obafemi Awolowo

Olope.

Ijoba U P P dapo mo N C N C gba ile, ile ati dukia awon omo egbe Afenifere nwon tun gba ohun ini N I P C ti o je wipe awon omo egbe Afenifere ni o nse olu'ari re

Ore wo ni ekun nba aja se ko se awon olorin ni o nkorin kan pere aberebere, abi won bi won. Ore Emi aja le belu ...

Olotu, e ku ise o,
Emi ni
J. Ola Wins
Itire – Suru-lere



Oloye S. L. Akintola

Irepo wo ni o wa le wa larin awon egbe mejeji nigbati o jepe awon egbe ti npa oruko won da bi ole ni o ba egbe Afenifere je ti gbogbo kamose ninu egbe na yo

## A Ngbadun Itan Yi

Iun mi yio dun pupo bi Olotu iwe Irohin Imole ba le gba mi ni aye die ninu iwe Irohin Imole lati dupe lowo ogbeni J. O. Shoyinka fun itan aladunto njade ninu iwe Irohin Imole ti a nka lojojumo itan na dun mo wa ninu lopolopo O si tun je ayo wa lati ma ka awon itan alarinrin ninu iwe nyin

Awon Yoruba lo npa lowe pe, bi enia ba se ni ni o e ti a ko ni owo lati fun ki alu ni ego enu pe, ... se pupo be na a dupe lowo enit nk itan Ajran Ilu awon Oku pe, o se pupo, ko si eniti yio ka itan na ti ko gbadun re, a ife itan na nigba gbogbo, o je itan alaiyebaiye, o fun awon ti nka ni tara isiuri leri awon omo Onilogbo, iru isoro ti nwon ba pade ati bi nwon ti nse bo lowo isoro na.

Nitoto o to bi idahwo nla ba defenia yio gbagbe gbogbo ohun ti oba ni lese kaina.

Mo dupe lowo olotu fun aye ti e gba mi, adele bare, ariannakore

Emi ni,
J. O. Akintade
Tamale Ghana


# BI O BA NI Iwe—Tite

FUN

**Lilo nibi ise re tabi orisirisi iwe itufo tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KOWESI ILE—ISE—ERO ITEWE

**Modupe Printing Press**
16 Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ERO ITEWE WA NHAN
*OWO POKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lęękanşoşo k o ri iyato*



GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ati AYO NIPA "DYNAMIREN" TONIK

ALE-BI-ELE Egbogi Toniki awon Jamonu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Ako agbara ati Ajebidan ise Re lara Agbalagba Okunrin gbogbo



Bi are ara ba nmu o, nigbakugba fun wahala tabi ... sise ti o ko le jeun daradara, tabi ki o male sun daa ... okun losan tabi loru tabi awon isan ara re gbogbo ki se fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunle daradara won ise tabi wahala sise tabi fun awon alera gbogbo 'nyin ti ojo ori re (age) ba ti koja Ogbon odun o si de ,aderin tabi jube lo. Mo dupe "DYNAMIREN ni egbogi ti e nfe lati so ara di otun patapata, oju re a si jolo, eran ara re ti o ti hunjo yio hu re s'i dan pada. Ara re yio ma gbe kankan nigbakugba d'Are" nigbakugba yio salo pelu. Igba dun ati alafia yio de si o. Iyen daju. Bere Egbogi na ni Sobuza

Waterool Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14' Wakeman Street, Yaba

# Ikilọ Fun Ere Awọn Ẹyọ Adamu Orişa

ẸKO:- Ninu ofin ere Adamu orisa, ako fun ẹnikẹni ninu awọn Ẹyọ lati ma si asọ loju larin ede, Ẹnikẹni ti o şe bẹ, Ọba yio ba rojọ.

Ẹyọ ti ko ba gba iwe tabi ti ko ni Tikiti ko gbọdọ wọ Iga Ẹpo tabi ibiti nwọn npe ni Agodo.

Gbogbo awọn Ẹyọ ti o ba jade lati inu Iga oloye kọkan ni lati gba aşe ẹniti o ba jẹ Iga Ẹyọ wọn abọ.

Ẹyọ ti o nlọ, ko ma gba apa osi lọ, eyiti o mbọ ko gba epa ọtun.

Awọn Orisa ko gbọdọ ka Ẹyọ kan mọ Agodo Ẹyọ ti Orisa ba ka mọ Agodo ko gbọdọ sọ pe oo fẹ ti tulasi jade, nşe ni ki o lo ko si arin awọn ọtẹntin to joko ni Agodo ko si si Aga kuro lori rẹ.

Orişi awọn Ẹyọ meji ko gbọdọ wọ Agodo nigba kan na, Olukuluku ni lati wọ pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ, ko si şe ẹtọ fun awọn Ẹyọ Anikanrin lati ma ya kuro larin awọn ẹgbẹ rẹ.

Okuta şele gbarako
Onile omu teremu teremu
Mọlẹ Ajilu Mọlẹ Malaki

Ẹyọkẹyọ tabi Ẹyọ Fancy ti o ba pade Adimu tabi Oniko tabi Ọlọgẹdẹ lọna o lati sori ọpabata rẹ kodo eyi jẹ ami pe Ẹyọ na lọwọ fun orişa na.

Ẹyọ ti koba gbawe
Ki gbọdọ dagodo
Agodo iga ẹyọ.

---

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Irọlẹ ọjọ oni yio sun wọn, gbemi le akoko ti o nfẹ gan.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ohun kan ti yio şe o ni anfani ni akoko kan lọjọ oni yio şẹlẹ si ọ lairo tẹlẹ.

ARIES (Mar 21-Apil 20) Ileri kan ti nwọn şe fun ọ ni ibi işẹ rẹ nwọn o mu ileri na şẹ fun ọ.

TAURUS (April 21 -May 21) Şọra nitoripe awọn ẹlẹrieke fẹ dide si ọ. Şọra rẹ lọdọ awọn alabaşişẹ rẹ tabi awọn ọrẹ buruku to foju han bi ọrẹ nwọnyi.

Gemini (May 22 - June 21) Ohun kan ti o ngbe ro lati şe şugbọn ti iwo ko mo akoko ti ole bẹrẹ rẹ, fi suru si

Cancer (June 22-July 23) Ohunkan ti o fẹ şe nile ati lode yio yori si rere bi o ba lese nkan na.

Leo July (24 - Aug 22) Sọ irin ẹsẹ rẹ ki o ma si şe ba ẹlẹgbẹ rẹ kanja nitori pe ohun ti o ngba ni ero yatọ si tirẹ

Virgo (Aug 23 - Sept 23) Maşe şori kunkun nigbati ọgarẹ ba paşẹ pe ki o şe ohun kan ti o le jẹ, tẹrba fun iwọ yio si jere rẹ

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Orire pupọ lo şi mbẹ fun ọ şugbọn ararẹ mọ nipa fifi aşiri sẹ pamọ jẹki ẹnu rẹ mẹrun

SCOPIO (Oct 24-Nov 22) Şọra ki o ma ba fi iwọ kọrun ninu ero kan ti o nro Iwọ yio ri ere rẹ gba lọna mirar.

SAGITARIUS (Nov 23-Dec 21) Ninu işẹ Ojojumọ ti o nşe ni ọna asiriki rẹ na, o dara ki o ko ara rẹ nijanu

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Ẹnikan wa ni tosi rẹ ti o nwo oju re fun iran tọwọ fun ni iranlọwọ.

---


## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu bun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbirọfi ko le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ şe Ofo mo

Bere fun egbogi awọn ara, Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhahan, atamatase egbogi fun, Ikọ here, Ikọ otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igbaiya, Ikọ lile, Ikọ, ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu

Bi o ba dan Igo kan PORAL yi wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si sun fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orişirişi Egbogi Ikọ miran ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
Phone: 2278 (Ọj. Ita Faji)
8, Palmchurch Street, Lagos Nigeria

---

## EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



### "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe şe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a mupo owo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu ẹgọu ti o le şe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun berẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o berẹ nipa aiko mẹ şe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbongi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani şeşe wa idi rẹ kio si panwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata gbẹro Naijiria iskejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji


---

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ keje oşu kẹfa (7/6/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

# Oloye D. O. Iroko Se Odun Egungun

MUSHIN:— Enia po lo bi ile bi eni ni Ojo ti Oloye D O. Iroko ti şe Baba Egbę Oję Atun-ohunse şe ianwo odun Egungun ni ojo keji oşu karun ninu ile re ni Odi-olowo Mushin awon oje po, ako mo egungun yato si enia, gbogbo adugbo na kun ko gba ęşę.



Oloye D. O. IROKO

Bi oti di pe ojo inawo egungun na ku ola ni awon enia ti nde lati Abęokuta. Ijębu-Ode, Shagamu, ętta Ibadan, Ilaro, Awon oję ti ilu Eko, Yaba, Ebute-Mętta Shomolu, paapa ti Mushin ko lonka.

Bi nwon ti nse bęnna ni nwon nso, akara lo bi rere, olęlę kelonka, iresi, amala iyan ati gbogbo nkan tięnu je po ni ojo na, eyiti enia ba fę ni awon fun.

Awon oti bi bia, sitaot, jinni, sinapu borandi ati awon oti aladun bi fanta mirinda sębin opu, misan, lo jara, a ko le wa so ti emu, inawo ojo na bu saya ole gongo.

Ko si ko ję ajeti ninu onję ati amuti ninu oti, gbogbo ara adugbo ni nwon ha ni onję ni ojo na.

Awon egungun paapa wa pidan okan ko joka ui ojo afi eniti o ba de bę lole fi ęru so iru inawo ojo na.

Dię ti aye wa fun lati daruko ninu awon to wa lojo na niyi, awon ęgbę oję to fi oloye na ję baba egbę shobayo Alagba-Odi-Olowo Alaga/Alaran Ande Gbwa, Akowe/Alaga Akindele Awolola olota, Ojo Awolola Eiyęsorun, Rasaki Elemel Akerę Adegbola Atokun, Iyaafin Adukę Elemele iya ęgbę Oję, saf-Ewewumi Iya Agan odi-olowo, Abębi Ajanaku iya Moję, sęgilola Morgan Akowe Obinrin.

Ati ęgbę Oloję Agbo ile Iroko lati Eko ęku ewu odun, aşeyi şamodun o asę.


## SEDO — PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awon ilera tabi amodi wonyi ba nyo o lęnu lode ara, owo tabi ese hihun tabi yiyun nigbakugba, Alefo, Egbo esę orişirişi tabi ti ojo rę ti pę bi udarin egbo ekusę tabi ekusę tabi lapalapa, Ela tabi ara sisu, Ako, inarun ati orişirişi arun "Ara" miran gbogbo



Gbiyanju lati dan egbogi tuun awon ara Ilu Tatanbu bulu şe ti nwon npe ni "PAYAL" wb larin ojo męta iwo na yio ma rohin re fun awon elomiran pelu Egbogi ipara yi ki se awon robirobi ti won nta kakiri ilu ni owo poku. Ojulowo egbogi arun arun ara haunhaun ti ko si gise ye meji ninu eleyi si yato patapata si awon ęgęremiti adimowo ti won nta kakiri igboro ati ni egbereko eqo bo pelu Orisi meji re lo wa Kekere ati Nla

Bere egbegi Ajebidan SEDO PAYAL yi ni şobu awon:

PILENAB MIXTURE.

Egboigi olomi dara julo fun awon omode ti jedijedi bi ako gbonse dede ba nyo leru bere ro ni

WATERLCO MEDICINE STREES
FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.



## MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupę Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No. 710 WEDNESDAY JUNE 3, 1964 (2D)


## E Lọ Bu Apa Fun Ọmọ Nyin

EKO:— Ni deede agogo meji ọsan ana ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ keji oşu yi ni Irohin kan wa lati Ile işe Minisita Alamojuto eto ẹkọ fun Apapọ Ijọba Naijiria pe, gbogbo awọn ọmọ Ile iwe ti nwọn yio ba fi oruko silẹ ni ọdun yi lati be rẹ ile iwe ni ọdun ti mbọ gbọdọ ni iwe ẹri penpe kan lọwọ pe, nwọn ti lọ bu apa n inu ile işẹ awọn alamojuto eto Ilera

Irohin na fi ye wa pe, Ijọba y o bẹresi ma a bu apa fun gbogbo awọn ọmọde ni ọla awọn ọmọ ti nwọn ba si ti bu apa fun, nwọn o ma a fun wọn ni iwe ẹri Iwe ẹri yi ni gbogbo awọn obi ọmọ na yio mu wa pẹlu iwe ọjọ'bi wọn nigbati nwọn ba mbọ wa fi oruko awọn ọmọ wọn silẹ fun ẹkọ ọfẹ ni ọdun ti mbọ.

Ikede na tun şe afikun pe, gbogbo awọn ọmọ ti ko ba ni iwe ẹri lọwọ pe awọn obi wọn ti lọ bu apa fun wọn, nwọn ko ni fi oruko ọmọ na silẹ bi o ti wu ki o ri,

Ikede na wa sọ fun gbogbo enia pe ni ọla ọjọ kẹrin oşu yi, ni ki awọn obi ma a lọ bu apa fun awọn ọmọ wọn ki nwọn si tọju iwe ẹri ti nwọn ba gba daada, nigbati nwọn ba si mbọ wa fi oruko awọn ọmọ wọn silẹ ki awọn mu iwe ẹri na lọwọ.

# ỌDARAN KAN GE APA ỌRẸ RẸ NITORI IFE ẸMU KAN !

KALABA:— Gbogbo ile ẹjọ lo kunsọọsọ ti ẹsẹ ko si gbero fun Ogunlọgọ Ọkẹaimoye enia to nwọn wa si ile ẹjọ nigbati awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, Akpan Ibang, ẹni Ọdun marundinlogoji ti o nşe işẹ ẹmu wa siwaju Adajọ Agba ile ẹjọ kekere Kalaba fun ẹşẹ igbidanwo lati pa enia ni Ọjọ Abamẹta ti işe Ọgbọnjọ Oşu karun Ọdun yi.

Alaye ti awọn Ọlọpa ti o ba Ọdaran na şẹjọ şe niwaju udajọ ni wipe ni Ọjọ Eti ti işe Ọjọ kẹtadinlogun Oşu kẹta Ọdun yi ni Oloye kan EkpoEdedi ku ni agbegbe kan ti nwọn npe ni Akpa Buyo ti gbogbo awọn enia inu ilu na si lọ sibe lati lọ şe isinku.

Nigbati nwọn sin Oku Oloye na tan ni awọn Ọmọloku ba gbe onjẹ, ẹmu, Ọti, siga, obi abata ati gbuja şilẹ ti gbogbo awọn enia na si njẹ, nwọn ngmu, nwọn nyọ.

Nibiti nwọn gbe ti njo ti nwọn nyọ ni Ọgbẹni paul ti o wa sibi inawo na lati ilu kan, Ikoti ti ko jinna pupọ si agbegbe na ba dide pe ki on na a jo.

Şugbọn bi o ti fẹ dide ni agolo aaşa rẹ ba bọ sinu ife-ẹmu ti ọdaran na bu kalẹ ti o fẹ mu, Ọgbẹni Paul si mu agolo aaşa rẹ ninu ife ẹmu na, ti ọdaran na ba sọ di ija, gbogbo eto inawo ti nwọn nşe ni ọjọ na si daru patapata ti kofi ni ojutu mọ

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn alagba ti nwọn wa nibẹ ni ọjọ na ba pe awọn mejeji sọdọ, nwọn si pari ija na fun wọn ko si tun ninu ọdaran na.

Nigbati gbogbo awọn ala basẹyẹ ọjọ na şetan ni gbogbo wọn ba lọ si ile wọn, şugbọ ọdaran na lọ duna de ọgbẹni Paul loju ọna, o si sọ fun un pe 'Apania ni iwọ yi, o fẹ pa mi, emi ni ngo si kọkọ pa o ki o to pa mi."

Lẹsẹkẹsẹ ni ọdaran na ba yọ ada jade ni abẹ ẹwu rẹ o si ge ọgbẹni Paul ni apa kan silẹ pegede. O tun şa ni ada lẹgbẹ, lẹsẹkẹse ni ọgbẹni Paul ba fi ariwo ta, ti o si nkigbe

Lojukanna ni awọn aladugbo de, nwọn si ba ọgbẹni Paul ninu agbara ẹjẹ pẹlu ọwọ rẹ kan nilẹ, şugbọn ọdaran na ti ada rẹ bọ akọ o si fẹ ma a salọ.

Sugbọn nipa iranlọwọ gbo bo awa aladugbo ti nwọn gbo igbe ati ariwo Paul ti o nke pelu ohun rara, nwọn tete jade, nwọn si ragabu ọdaran na ki o to salọ.

Nigbati Ọlọpa na şe alaye ẹjọ rẹ tan ni adajọ wa yi oju si ọdọ Ọdaran na, o si bi lere kini ohun ti o fẹ sọ si ẹjọ ti awọn Ọlọpa ro silẹ yi.

Ọdaran na ko tilẹ tiju rara nşe ni ole ojukoko si adajọ ti o si sọ şako pe, "O jẹ ogun eewọ ni adugbo awọn ne ki ẹnikan ti ọwọ bọ ẹmu ti ẹlomiran fẹ mu ko si ẹniti ole gba iru rẹ, nitorina mo şe akiyesi pe, apania ni ọgbẹni Paul, mo si pinnu lati da sẹria ti o tọ ati eyiti o yẹ fun un.

Bi o ti sọ ọrọ yi tan gbogbo awọn ero kotu lo mi imi ẹdun nigbati Ọgbẹni Paul yo ageku apa rẹ jade labẹ aşọ ti gbogbo wọn si dorikodo.

Lẹhin eyi ni adajọ paşẹ pe ki ọdaran na lọ si ẹwọn ọdun mẹta laifarabara.


## Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De

Bere Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

## 'CORSIVER'S



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a şe ni pataki Fun „ARỌN KINIŞA" tabi LATANATAN" ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹrakụ tabi lati ma şe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba i lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ebin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ihadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu ilẹ lẹ lere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo şe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni şọbu awọn.

Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.
ATI NI AWỌN ŞỌBU IBADAN:—
IŞẸ LODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA


## Awọn Oşişẹ daşẹ Şilẹ

Lati Oju Ewe Kini

adajọ sọ pe ki o ma a lọ si ile lori iduro ati onigbọwọ o si yẹ gbigbọ ẹjọ rẹ si ọjọ iwaju.

A lero pe awọn osişẹ yio pada si ẹnu işẹ wọn ni owurọ yi, nigbati nwọn ba gba iwe ipinnu Apapọ Ijọba lori iwadi owo oşu awọn osişẹ, eyiti o da idaşẹsilẹ na.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21958
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Cambell Street, Lagos (3/6/64)